IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 601 SATURDAY MAY 9, 1964 (2D)

## Ọlọla Majẹkodunmi Nlọ Si Ilu Oyinbo

IKOYI:— Ni deede agogo marun irọlẹ ana ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi ni irohin kan tẹwa lọwọ lati ile iṣẹ Minista Alamojuto eto irohin fun Apapọ Ijọba Naijiria pe, Oloye Dokita Moses Adekoyejọ Majẹkodunmi, Minista Alamojuto eto ilera fun Apapọ Ijọba Naijiria ti iṣe Oloye Maiyegun ilu Eko yio lọ si ilu Oyinbo ni ọla ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi.

Irohin na tun ṣe alaye siwaju pe ilu Dublin, ni Ilu Ọba Gẹẹsi ni Dokita Majẹkodunmi nlọ ninu ile ẹkọ giga/nlọ. Ohun ti o si nlọ ṣe ni ọhun ni lati gba Oye ninu iṣẹ Dokita.

Onirohin wa kan fi ye wa pe ni deede agogo mejọ alẹ ọla ọjọ Aiku ni ọkọ Dokita Majẹkodunmi yio kuro ni Ikẹja

Agbọ wipe gbogbo awọn oloye Eko, Minista ati awọn enia sarakisaraki ni nwọn o ba Dokita na de Ikẹja nibiti ọkọ ofurufu na yio ti gbe lọ si ilu Oyinbo,

Irohin na fi ye wa pe ni ọjọ karun osu ti mbọ yi ni oloye na yio de Awa oniwe irohin Imọlẹ ki Dokita Majẹkodunmi pe alọ adara, abọ asun wọn o,

### Agbẹjọro Ijọba Ti Pari Ọrọ Rẹ

# OLAWOYIN KO NI ẸJỌ LATI JẸ NIWAJU ADAJỌ !

EKO:— Ọgbẹni Duro Adebiyi agbẹjọro pataki fun Apapọ Ijọba Naijiria ti o ti bẹrẹsi sọrọ lori ẹsun iditẹ si Ijọba ti Ile ẹjọ nla mba Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ṣe ti pari ọrọ rẹ niwaju awọn adajọ na ni ọsan ana lehin ti agbẹjọro na ti sọrọ fun odidi ọjọ marun.



Ogbẹi 'Duro Adebiyi
*Agbẹjọro Ijọba*

Agbẹjọro na ti pari ẹjọ rẹ lori awọn enia merin yoku ni owurọ ana, eyi lo si mu u di enia mẹtadinlogun ti o ṣe ẹjọ wọn pẹlu Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ,

Siwaju eyi ninu ile ẹjọ na ni Ọgbẹni Adebiyi bẹrẹ ọrọ rẹ lori ẹjọ ẹniti Adajọ Agba Ṣowẹmimọ sọ si ẹwọn



Ogbẹni J. S. Olawọyin

ọdun meje lori ẹsun kanna

Ọgbẹni Adebiyi ni ẹlẹri ti o daju, Ọgbẹni Kehinde, ti ile iṣẹ ẹlẹnrọki sọ niwaju adajọ pe on ri OmisaJe ati Onitiri ninu ile iṣẹ wọn ni alẹ ọjọ kan.

Nigbati Henry Oleari ẹniti iṣẹ ẹlẹri karun Ijọba sọ fun Omisade pe on ko mọ ibi kan ni Eko, Omisade ṣe ileri pe on yio mu Oleari kakiri gbogbo ilu lati mọ larin Eko.

Ọdẹsanya: "Njẹ Onitiri ba wọn lọ si ibi Magazine?"

Veha: "Kẹhinde sọ wipe pawa Teşan B. ni nwọn de ṣugbọn ẹlẹri, miran tun sọ wipe pawa A ni Ewo ni ki a gbagbo ninu mejeji?"

Adebiyi ka akọsilẹ na lati inu iwe ṣugbọn adajọ ko faramọ.

Veha: "Bawo ni nwọn ti ṣe lọ si Pawa B ti ẹnikan si sọ pe, pawa A Teşan ni" ?

Adebiyi: "Oluwa mi ohun ti o wa ninu iwe ni mo ti ka fun yin yi."

Mbanefo: "Adebiyi lọ wo oju ewe kọkandinlọgọjọ (page 169)

Adebiyi: Mo ti ri i, ṣugbọn ki nto le dahun ọrọ na, ẹ jẹki nkọkọ sọ ẹjọ mẹta ti Omishade ro fun awọn Ọlọpa na ki nto dahun ibere yi.

Ọgbẹni Adebiyi sọpe Omishade ti gba wipe, on lọ si Ghana ni igba meji. Ọrọ mẹta ti o ya



Oloye Awolọwọ

tọ si ara wọn, ti ikan ko si farajọ ara wọn ni ẹjọ mẹtẹta ti o ro fun awọn Ọlọpa ni Teṣan,

Ninu ẹjọ ti Omishade ro ni Taşan ni pe, "Mo lọ si Goana, nigbati mo de Ghana,



Ọlọla Ade. Ademọla
Olori awọn Adajọ

ile obinrin kan ti nwọn npe ni Sikira ni mo de si. Sikira na ti ni ọkọ ki iṣe ọlọmọge ọmọ Ilẹ Naijiria ni."

"Nigbati mo de ọdọ rẹ, o fun mi ni onjẹ, nko si san owo fun onjẹ na, ọfẹ ni

Ọgbẹni Adebiyi ṣe alaye pe, eyi ni ẹjọ kini ti Omishade ro fun Ọlọpa ni Teṣan, o si tun ro ẹjọ miran eyiti o wa ni oju ewe kẹrinla (page 14) nibiti o ti tun sọ wipe:

"Ayọ Adebayọ pe mi pe ki nkalọ si ipade kan ni Ibadan, ṣugbọn mo kọ lati lọ si ipade na, Nwọn so fun mi pe, mo gbọdọ lọ si Ipade na ni,"

Nigbati a de ipade, nwọn sọ fun mi pe ki ngmura lati lọ si Ghana, nigbati a si de Ghana, a gbe ọjọ mẹrin pere ni Ghana ki a to pada si Naijiria"

Nigbati mo de lati Ghana ni mo wa nse ipalẹmọ iyawo afẹsọna mi, ti mo fẹ gbe laipẹ"

"Ṣugbọn nigbati mo ri Jakande nigbati mo de, o sọ fun mi pe, nibo ni mo ti wa? nitori on (Jakandej) ti wa ohun kiri ti pẹ nitoripe ipade kan wa ni Ibadan ti on gbọdọ lọ"

"Ninu ipade na ni nwọn ti yan mi wipe, emi ni ki nlọ ṣe abẹwo ile-iṣẹ ẹlẹntriki ni Ijọra ati Ibudo ọkọ ofurufu Ikẹja"

"Ki iṣe emi nikan ni nwọn ran, emi ati ọgbẹni S. A. Onitiri ni, a si jijọ lọ ni pẹlu."



Ọgbẹni Onitiri

"Nigbati mo nlọ Ikẹja, emi ati Henry Oleari ni ajijọ lọ: nigbati mo de, mo pada lọ jiṣẹ ohun timo ri ni bi mejeji ti mo lọ, mo si tun sọ fun ọgbẹni Ayọ,

Wo Oju Ewe Kẹfa

**Njẹ Oke—Iṣoro wa fun Ẹ Bi ?**

FUN IWADI OHUNKOHUN KỌWE SI WOLI

D. Abiọdun,
P. O, Box 1554,
Lagos, Nigeria.

Jọwọ fi Stampu tọrọ ati address rẹ ranṣẹ si wa lati tete da esi pada ni kiakia.

# IWE SI OLOTU

## Ilaro Nfẹ Itọju Ijọba

OLOTU inu mi yio duu bi ẹ ba legba mi ni aye ninu iwe yin oloyiumọmọ lati si Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati se ayẹwo gbogbo awọn ọpọlọpọ awọn nkan ti o yẹ ki Ijọba ṣe si ilu Ilaro ti nwọn fi silẹ laiṣe.

Inu wa yio dun bi Ijọba ba le e gẹgẹ bi ina Ẹlẹntiriki to wa ni arin ilu na ki o de ọpọlọpọ awọn ọna ti ina na ko de rara ati papa omi ẹrọ to wa ni ilu na ko pọ rara

Eyi yio jẹ inu didun fun wa bi awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ba le ran wa lọwọ ki awọn gbogbo nkan wọnyi le tẹte de ọwọ wa ati pe gbogbo awọn nkan miran to jẹ pe osi ntẹ ilu na ni ile ifi owo pamọ si ki osi to bi mẹrin ti yio wa ni ilu na nitori ilu Ilaro ki iṣe ilu kekere rara inu wa yio dun lọpọlọpọ bi iranlọwọ awọn nkan wọnyi ba le wa fun wa mo dupẹ o, Olotu

Emi ni
Bisi Okunọla

ILARO

## Bakare Ẹku Iṣẹ

Ẹ dakun ẹgba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin Oloyin mọmọ ti njade lojojumọ lati dupẹ lọwọ ọrẹ wa Ọgbeni Ramọnu Adio Bakare fun ifẹ rẹ ti o ni o si ilu rẹ, mo gba fun ọrọ rẹ na fi o mu Ọgbọn lọwọ ti ko si tiju lati sọ ẹdun ọkan rẹ jade fun araiye gbọ.

Ko si Ọmọ ilu Omupo ti inu rẹ ko dun si imọran rẹ na pe, ki gbogbo awa Ọmọ Omupo ni ẹgbẹ kan soso ti ko ni faramọ ẹgbẹ iselu kankan rara, ti ko si ni di ẹgbẹ iselu ti ẹnikọọkan wa nse lọwọ rara.

Nitorina mo nbẹ gbogbo ẹgbẹ to wa ni ilu Omupo jẹ ki ronu wa danda ti a si tele ọrọ ti Ọgbẹni R. A. Bakare sọ ki a wa na wa ilọsiwaju ilu wa nipa jijọ da ẹgbẹ kan silẹ ti yio mọ mojuto ilọsiwaju ati anfani ilu wa gẹgẹbi awọn miran ti mọ ṣe.

A mo dupẹ lẹkansi emi si nreti Ọrọ ti awọn Ọmọ ilu wa yio mọ sọ si ọrọ yi.

Olotu ẹ ku sẹ o, ajinde ara yio mo jẹ o amin.

Emi ni
Jimoh Ẹlẹmọ

EKO

## Ọrẹ Mẹta Ẹ ku Iṣẹ

Mo dupẹ lọw olotu fun aye ti ẹ gbami ni gbogbo igba ti mo bati kọwe. Mo tun dupẹ lọwọ awọn ẹgbọ isowo pọ mẹta ti ilu Ijọmu fun lala ati akitiyan wọn lori fifi ọjọ igbeyawo si ọjọ kan na ni ilu Ijọmu ni ọdun yi.

Gegebi eto aṣọ ẹgbẹjọda ti si awọ ọkọ iyawo toda edeaiyepe nilẹ nipa pe aṣọ di orisi mẹta ti tiwọn yio da ni ẹkanṣoṣo. Ẹjẹ ki a fi ọju inu wo aṣiṣe na daada ki atete yago kuro ninu iru aṣiṣe ba yi.

Awọn Yoruba ni agbajọ ọwọ ni afi sọya, ki Oluwa Ọba ran gbogbowa lọwọ amin. Ẹjẹ ki afi imọwa ṣọkan ki awọn kan ma ma gbe igi ki awọn kan si ma rẹ

Ijọmu

M. A. A Okiki

Emi ni

nilẹ ma.

Bi aba ṣe ara wa ẹjẹ ki ama fi ara wa sun arawa sun arawa ṣẹ ki nbiọ ni ogun ọrẹ bi aba ni ao mafi oro ya oro lailai oro ko ni tan nilẹ.

Ẹjẹ ki ama fi ifẹ ba ara gbe ni tori awọn ti yi tẹle wa ki nwọn le ba ifẹ larin ilu wa.

## Imọle Eyi Ko Ye Mi

Jọwọ gba mi ni diẹ ninu iwe rẹ oloyin mọmọ to njade lojojumọoti o kun fun ọgbọn ati oye lati berẹ ọrọ ti ko ye mi yi lọwọ awọn orimaimọ ati awọn ojulowo Musulumi ti nwọn mọ itumọ awọn esin Imọle daada ti ki ṣe alawọṣe tabi awọn tio sa nṣe bi wọn ti nṣe lai mọ itumọ nkan ti e awọn as wa nsṣe

Ibere mina ni pe, mo ṣe akiye I Pe ni ododun ni awo Musulumi orilẹ-ede aiye ma ẹran, mo fẹ mọ idi pataki ati itumọ rẹ ti nwọn fi npa ẹran na atipe nibo ni nwon ri oruke ti nwọn fi npe ni ILEYA ti jode?

O dabi enipe Ueya pipa ko jẹ nkan kan lodo Ọlọrun bi ko ṣe ki a bẹru Ọlorun ki a si tun sin tokantokan wa. Mo ri kọ ninu Alukarani pe ẹran tabi ẹjẹ ẹran ko le de odo Olorun, ṣugbọn eyi ojẹ iṣewe gba niwaju Re ni ibẹru Rẹ (Sura 22 Aya 37).

Emi ni
Young Ade

AKINMỌRIN

## Ẹla Eyi Ye mi

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye diẹ ninu iwe rẹ Oloyin mọmọ ti nkọ wa ni ọgdọn ati oye lati bere ọrọ mi yi lọwọ awọn ọjọgbọn ti nwọn le mọ oyun inu igbin ati awọn Alagba a i awọn alagba ti a nkọ iwe sinu iwe IROHIN IMỌLE ti nwọn si tun nka iwe na pẹlu.

Yio jẹ didun inu mi bi awọn onkawe Irohin imọlẹ ba le fun mi ni esi kikun fun ibere mi na

Ibere na lọ bayi nigbana nẹ iyọ wọn ni ilu Naijiria ati ekeji Nigbawo ni Ijọba nmojuto ọja tabi (cootrol) ni ni ilẹ Naijiria

Ato awọn merin ti onjiyan si asiko awọn nkan mejeji yi sẹlẹ ti a ko si mẹ ojutu rẹ rara n agbalagqa kan ba ni ki a kuku fi sinu iwe Irohin Imọle ki awọn ọlọgbọn ati oloye ki o le la ọrọ na ye wa dada.

Mo tun dupẹ fun anfani ti olotu iwe Irohin Imọlẹ nfun wa lat mọ kọ ọrọ sinu iwe Irohin Imọli Paapa ọrọ awọn ara Agbegbe Igbomina ati awọn miran kakiri ilẹ Naijiria.

Emi ni
K.A Alashalẹ

EKO


BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16 Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o ri iyatọ*


## IWE ITUMỌ ALA

Josẹfu Alala ti ẹ ti nkan ninu iwe Irohin Yoruba ti jade ni odindi fun tita nisisiyi.

OHUN TI O WA NINU IWE NA

1. Egbogi Ajẹbidan agbabiętu.
2. Odu Ifa mẹrindinlogun lati ma a fi yẹ itumọ ala rẹ wo.
3. Ẹnikẹni ti o ba ra iwe yi ni anfani lati bere ala rẹ nigba gbogbo lọfẹ lọwọ Josefu Alala.
4. Koiti si ikeji rẹ ninu iwe itumọ ala ti o ti njade ri nitoripe JOSẸFU ALALA ni o ṣe e

Tete ra tirẹ loni ki o to tan.

AKIYESI

A tun nfẹ asoju ti yio ma ba wa ta iwe na, owo pọọku ni ao ta fun wọn ki nwọn ba ri ere gọbọi jẹ o ba fẹ se asoju wa kọwe fun iwe adehun.

Iye owo 5/- £2

**J. O. Shoyinka**
N/ Shittu Street
Ibaden

tabi
1, Isiba Street Odo Ẹran
c/o Postal Agent
Itirẹ,
Via Suru—Lere,
Yaba

## Egbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbe Imẹlẹ Aiye ni ọjọ kẹwa oşu karuu (10/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipape lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Akọwe Agba

# Itumọ Ala

**Aworan Aiye**- Iwọ yio ri iran kan lairotẹlẹ iwọ yio ri rere nibẹ.

**Afẹrẹ**- Ti oju orun ba şu dudu, ifarapa nlanla şoi itumọ rẹ.

**Aaake**- Ti o ba ri aake loju ala, şọra gidigidi aisan mbọ Ti nwọn ba fi nla igi iku ebi ni.

**Apo**- Apo ofifo fdamu ni eyi. Ti o ba wuwo, owo tabua yio yọ si ọ lọwọ laipẹ ojọ.

**Agbefọba**- Ti agbef. ba ba mba ẹ rojọ orire ni eyi ohun ti o ti ngnaga lati mu yio to ọ lọwọ.

**Apari**- Ti o ba ri apari loju ala, itumọ rẹ ni aisan ojiji tabi jamba airotẹlẹ ti o le gba emi.

**Asia**- Ami ogun ati ijan bọn ni eyi ti o ba nfẹ lẹlẹ, airojuraye ni itumo re.

**Apẹrẹ**- Ti o ba ri apẹrẹ, maşe jafara lati kun fun adura itumọ rẹ ni iku ojiji.

**Adan**- Ti o ba ri adan ni oju ala şora lati maa fi inu rẹ han eoia ki awọn ma ba gbẹhin şe ọ ni jamba.

**Awo koto**- Ti o ba jẹ ofifo, adanu ni itumọ rẹ Ti onjẹ tabi omi ba wa ninu rẹ aisan ni.

**Asọ ibusun**- Şora gidigidi ki o ma ba padanu owo gọbọi

**Agbon**- Ti o ba ta ọ ni ojuran aisan ojiji ni itumọ rẹ Ti o ba nkun ọ yunmuyunmu owo tabua mbọ wa fun ọ ni yẹn.

---

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 20-Feb 18) Ọjọ işẹ ni ọjọ oni a si ti şe ilana awọn iru işẹ ti o ni lati şe faaji iwọ pẹlu Obinrin yio miriogindi irẹpọ yio si wa larin iwo ati ọrẹ re atijọ

PISCES (Feb 19-Mar 20) Maşe jẹki ọrẹ ti ko to nkan nipa awọn ebi rẹ ba ọ ninu jẹ nitoripe yọ ni igbẹhin rẹ yio jẹ.

ARIES (Mar 21-April 19) Bi o ba nfẹ şe aşepari awọn nkan ti o ti dawọle ni aşeyori, nşe ni ki o wa eyiti o wulo ati eyiti o dara papọ awọn Ọrẹ rẹ ni yio seranlọwọ fun ọ nibẹ.

TAURUS (April 20-May 20) Dahun si awọn ibere to ba şe pataki ki o si kọwe si awọn ti o qa yẹ, şugbọn maşe ba egbẹ re kan gbonu ki ọrọ ibinu ma ba wọọ, maşe kọ lati wa ọrẹ kun ọrẹ.

GEMINI (Mar 21-June 21) Ire ni Ọjọ oni yio jẹ şọra iwọ ko gbọdọ fi gbọnmisi omi ko to ba ire oni na jẹ Bi inu ba mbọ, nşe ni ki o lọ fi ara tẹlẹ lọ sode lati kesi awọn ọre rẹ.

CANCER (June 22-July 22) Ọjọ re ati alafia li oni jẹ fun ọ şugbọn maşe yi aniyan rẹ pada, awọn ọrẹ atijọ yio fun ọ ni idunni iwọ yio si bọ sinu işẹ titun.

LEO (July 22-Aug 22) Ipade pataki kan wa fun ọ ni orun Ọjọ si mbẹ lese re Iwọ yio ri aleio ti yio wa ki ọ owọ re yio to owo dẹ

VIRGO (Aug 23-Sept 22) Ọrọ kan yio şẹlẹ siọ, bi iwọ ko si .au sura, yio di ogun yio di ode maşe gbonu, Irin ayọ kan yio te ọ lọwọ. Iwọ yio ri işe se nipa iranlọwọ awọn ojulumọre.

LIBRA (Işẹ ti o nşe lọwọ nisisiyi le ma t ọ lọrun şugbon Ọjọ ori yio ṣeşo fun

SCORPIO (Oct 24-No 22) Iwọ yio le fin opin si ọrọ pataki kan lo şe abewo awọn ọrẹ rẹ kọwe si awọn ito wa ni dale Şugbọn maşe wa mọlo loni.

SAGITTARIS (Nov 23-Dec 21) Aiye rẹ yio ma gbadun gbogbo amodi ti nşe ọ le dopin.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Gbogbo nkan yio ma dara fun ọ oju rẹ yio si ri gba ara gbọ iwọ yio si bori işoro gbogbo.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI NWỌN NPE NI RICHALET Eleyi yato patapata si awọn Robi-r bi. Işe re lara eniyan si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọna mọna

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di o w o Iyẹn şe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yen rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gegebi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranşẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Iatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju şuşu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ ba, arun Edọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si n ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu.

Şa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fuu ẹlomina pẹlu.

Bere Şọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

## Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin oba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tab ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikoto ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba **Igba** — aiya riru ọmu riro, didun ara atinu wa ni o ma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, efori tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gegebi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPENI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ aju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji tabi a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio şe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi t o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ apo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọna-ọfun didun, ati orişirişi omiran pẹlu wọn mbẹ ni şọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)
ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

# Oke — Amu Federal Union Ṣe Inawo Ọdun Ileya

MUSHIN: Irohin ko to afojuba ni inawo alarinrin ti ẹgbẹ Oke-Amu Federal Union na ni ọjọ Aiku ti ṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu kẹrin ninu ọdun yi ni ile Balogun ẹgbẹ na ni nọmba 3, Imasun Street, Mushin. Emapọ lọ bi omi, ero to wa woran kọ ni onka. Gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na lo pe sẹ siti ipade na tayọtayọ.

Bi o ti di owurọ ipade na ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nde lọkọọkan lati Agege Mushin, Eko, Ebute Mẹtta Yaba ati gbogbo ilu ti o yi Eko po ni awọn ọmọ na ti de ki o to di agogo mẹwa ti nwọn yio bẹrẹ ipade na.

Bi o ti di agogo mẹwa owuro ni ayẹyẹ na bẹrẹ pẹ lu oriṣiriṣi onjẹ bi iyan ọka ati irẹsi pẹlu, nigbati nwọn jẹun tan, ti onjẹ na tun ku silẹ, ni nwọn ba nna ile ati ọna gbogbo aladugbo ni nwọn ha ni onjẹ ni ọjọ na.

Awọn ti o nrekọja lọ paapa tun jẹ ajẹti onjẹ ni ọjọ na bi inu ile ti kun bẹna ni ita kun ti ẹniti o ba de ibẹ ko le da ọmọ ẹgbẹ mọ yatọ si alahejẹ. Inawo ọjọ na bu saya o le gongo, a fi ẹniti o ba de ibẹ ni o le fi ẹuu sọ.

Bi omi ojo ni nwọn nlo bia, Staotu, birandi, ginni, Ṣinapu a ko le sọ ti ọti aladun mọ, awọn yẹn lọ bi rẹrẹ, ko si wipe ẹnikan npin awọn ọti na fun enia; bọ sibẹ ki o mu tirẹ ni

Bi awọn ọkunrin ti nṣe ẹgbẹ tiwọn bẹna ni awọn obinrin wọn na si nṣe ipade ti wọn. Ọkan ko di ọkan iọwọ rara; bi awọn ọkunrin ti nnawo ti nwọn nnara awọn obinrin paapa ko duro mọ woran, awọe na nṣe ẹgbẹ ti wọn na lọ ni.

Nwọn wa bẹrẹ si jo ilu ni oriṣiṣi, gbogbo ere ti awọn bi Roy—Chicago, Ọlaiya, I. K. Dairo ati Ogunde ṣe sinu awo ikọrin ni ẹrọ ti ma da kọrin (Recording) wa ntu kẹkẹ orin silẹ, ijo ọjọ na, agbayanu ni.

Orukọ awọn oloye ti awọn ọkunrin ni yi, baba Isalẹ Tijani Okunlọla. Igbakeji baba Isalẹ Lamidi Afọlabi, alaga L. A. Aderohunmu. Igbakeji alaga T Oketunde, Balogun Gbadamosi Ọlaọrẹ. Igbakeji Balogun S. O. Ogungbade, Basọrun L. Adio Ayandeji, Akọwe L. T. Ọladeji, Igbakeji akọwe S. Ade. Ọladeji, akapo Rafiu Alabi, alufa Lawanl Ajibọla ati alaṣẹ ẹgbẹ K. Ọmọtọshọ.

Eyi si ni orukọ awọn oloye ti awọn obinrin, alaga Hunmani Adebayọ, igbakeji alaga Silifa Ọlaọrẹ, iya ẹgbẹ Rabi Okunlọla, igbakeji iya ẹgbẹ Safuratu Oketunde, Akọwe Nusiratu Ọladeji, akapo ati olori ni S. Ade. Ọladeji.

Nwọn ṣe ayẹyẹ na titi ti ilẹ ọjọ keji fi mọ, inawo ọjọ na pọ ti awọn ẹlomiran ko fi mọ ọna ile mọ. A seyi ṣamọdun, ọmọ rere ni ao fi ṣe ẹẹmi i aṣẹ.

## AKIYESI PATAKI!

Eyi ni lati kede fun awọn Onkawe IROHIN IMỌLẸ jakejado Ilẹ Naijiria pe ỌTẸLẸMUYẸ ti ti aio de nişişiyi. Ọrọ rẹ yio si ma a jade ninu IROHIN IMỌLẸ deede nişişiyi nitorina ki ọwọn onkawe wa mura silẹ lati ma a ka igilangọ urọ ỌTẸLẸMUYẸ ti yio ma jade ninu Iwe wa na,

OLOTU

## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ki o wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo Eran Itirẹ

## Apejuwe Ile Isẹ Wa

Ẹ Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni ti oba sokalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka<br>
c/o Postal Agent,<br>
Itirẹ Via,<br>
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | 20/- |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 25/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ilana Yanrin tite ati Etutu Şişe | |
| Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Isẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6 |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/6 |

J.O. Shoyinkan<br>
c/o Postal Agent<br>
Itirẹ Via Suru Lere,<br>
Yaba.

or 1, Ishiba Street (Odo Ẹran)<br>
ITIRẸ

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TONIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki wọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ṣẹ şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa da ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inn ko ba gunlẹ daradarawọn iṣẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo e nyi il ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun lọ si ded'adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara biọtun patabata, oju rẹ a si jọlọ, şran ara rẹ ti a ti huujọ yio bẹ rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igbadun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:-

Waterloo Medicine Store<br>
8, Palm Church Stree, Lagos.

